# Àwọn Atọ́ka Amúpé inú Èdè Yorùbá

**Ọládélé Awóbùlúyì**
*Adekunle Ajaṣin University*
*Akungba-Akoko, Ondo Sate*

## Ìfáárà

Bí ẹnìkan bá dédé wí pé

1. Mo gbọ́

Láìjẹ́ pé ó ń fèsì sí ohun tí ẹlòmìíràn ti ń bá a sọ bọ̀, a óò sọ pé gbólóhùn rẹ̀ yìí kò kún tó bí ó ti yẹ. Bí ó bá wáá tún ọ̀rọ̀ rẹ̀ sọ báyìí, tí ó ní

2. Mo gbọ́ ariwo.

Ìgbà yẹn ni a tóó máa gbà pé ohun tí ó wi ti kún tó. Amúpé ni ọ̀rọ̀-ìperí fun iṣẹ́ 'ariwo' _ ìyẹn, ọ̀rọ-orúkọ tí ó fí kún ohun tí ó kọ́kọ́ wí. Àbọ̀ ni ọ̀rọ̀ náà pẹ̀lú. Nítorí ìdí èyí, ẹ̀yà amúpé kan ni àbọ̀ jẹ́ nínú gírámà Yorùbá. Ẹ̀yà amúpé mìíràn ni 'pé Oyè kò tíì dé' nínú

3. Mo gbọ́ pé Oyè kò tíì dé.

Atọ́ka amúpé ni ọrọ-ìperí fún 'pe' tí o wà ní ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀. Ẹ̀yà amúpé keji yìí ni ọ̀rọ̀ dá lé lórí nínú àpilẹ̀kọ ráńpẹ́ yìí.

## Pàṣí-pààrọ̀ Atọ́ka Amúpé

Bamgboṣe (A Grammar of Yoruba; Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá, o.i. 210) ni ẹni tí a mọ̀ tí ó kọ́kọ́ tọ́ka sí i nínú gírámà Yorùbá pé 'tí' dígbá máa ń bá yìí:

4. Iṣu ni mo rà tí mo kó sínú apẹ̀rẹ̀ ti mo sì ní kí ó máa ṣọ́ dè mí.

Atọ́ka amúpé ni 'ni' kan tí ó kù sínú àpẹẹrẹ yìí. Kò sì sí wúnrẹ̀n mìíràn tí ó lè rọ́pò rẹ̀; bí bẹ́ẹ̀ kọ́ (4) kò níí lè ṣiṣẹ́ gbólóhùn mọ́. Ṣùgbọ́n kí ni ti 'ti' ti jẹ́ níbẹ̀? Ṣé kànńpá ni ìjẹyọ rẹ̀ níbẹ̀ àbí kànńpá kọ́? Ìdí tí ìbéèrè yìí fi wáyé, tí ó sì ń fẹ́ ìwádìí síwájú sí i, ni pé kò jọ pé (5) wọ́pọ̀ rárá.

5. Iṣu ni mo rà ni mo kó sínú apẹ̀rẹ̀ ni mo sì ní kí o máa ṣọ́ dè mí.

Bí (5) kò bá wọ́pọ̀ tí kò sì dún dára létí tó (4), bí àwa ṣe rò, a jẹ́ pé kànńpá ni ìjẹyọ 'ti' níbẹ̀.

Ìbéèrè mìíràn tí a tún ní láti ṣe nípa 'ti' kan náà ni pé, ṣé òun náà ni a rí tí ó jẹ yọ nínú (6)?

6. Iṣu tí o ní o rà dà?

Bí ó bá ṣe òun ni, a jẹ́ pé atọ́ka amúpé tí ti inú (6) jẹ́ ni òun náà jẹ́ nínú (4).

**'Tí' Gẹ́gẹ́ Bí Gbogbonṣe Atọ́ka Amúpé**

Gẹ́gẹ́ bí a ti wí ni òpin ìfáárà lókè, atọ́ka amúpé ni 'pé'. 'Tí' dígbà máa ń rọ́pò òun náà nínú gírámà Yorùbá. Àpẹẹrẹ ni:

7. Nítorí pé ó lọ tí kò dé tí kò sì fohùn ṣe méjì tẹ́lẹ̀ ni mo ṣe ń bínú sí i.

Kò sí atọ́ka amúpé mìíràn tí ó lè rọ́pò 'ni' nínú àpẹẹrẹ yìí fún ìdí kan náà bí ti (4) lókè. Síwájú sí i, bí ó ti rí fún (7) níbí yìí: kò jọ pé ìwọ̀fún ni 'ti' fi rọ́pò 'pé' níbẹ̀. Àwọn àpẹẹrẹ mìíràn ni:

8. (a). kì í ṣe pé mo débẹ̀ tí mi ò kí gbogbo àwọn ará ibẹ̀.
   (b). pé ó lọ tí kò sì fohún ṣe méjì tẹ́lẹ̀ jọ mí lójú.

Bí a bá fi lé ti àpẹẹrẹ wọnyìí, ó jọ pé bí ó ti rí fún (4) náà ni ó rí fún wọn: 'pé' kan gbọ́dọ̀ ṣẹ́kù sínú wọn[1]. Ìyẹn nìkan kọ́; níbi tí a rí ìṣesí ẹ̀yà amúpé yìí dé, ó jọ pé àti àwọn tí ó ń ṣíṣẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ (bí ti inú (8b) àti àwọn tí ó ń ṣe ti ẹ̀yán (bí ti inú (7)) (wo Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá, o.i. 69 & 65) ni ó máa ń fàyè gba pàṣí-pààrọ̀ 'pé' òun '*tí*'.

Yàtọ̀ sí pé 'tí' lè rọ́pò 'ni' àti 'pé', ó lè rọ́pò 'bí' bá kan náà tí ó jẹ́ atọ́ka amúpé awẹ́-gbólóhùn káni (conditional clause). Àpẹẹrẹ ni;

9. (a). Bí kò bá tètè dé. Kò níí bá mi níbí. / kò níí bá mi bí kò bá tètè dé.
   (b). Tí kò bá tètè dé, kò níí bá mi níbí. / kò níí bá mi tí kò bá tètè dé.
   (d). Bí ó bá tún ọ̀rọ̀ rẹ̀ sọ, tí ó ní…

Àmọ́ o, kí á kíyèsí i pé 'tí' kì í rọ́pò 'bí' nínú awẹ́ gbólóhùn káni tí kò ní 'bá' nínú.

Àpẹẹrẹ ni:

10. (a). Bí o fẹ́, bí o kọ̀, a jọ máa lọ ni. (*Tí o fẹ́, tí o kọ̀ …/?Bí o fẹ́ o fẹ́, tí o kọ̀…)
    (b). Bí ó jí láàárọ̀, kò níí bọ́jú. (*Tí ó jí láàárọ̀, kò níí bọ́jú.)

Bẹ́ẹ̀ ni kò lè rọ́pò 'kí' rárá nínú (11) bá kan náà.

11. Kò ṣẹlẹ̀ rí kí o jí lọ ìbàdàn, kí ó lọ tajà lọ́hùn-ún, kí ó má sì padà wá sun ifẹ̀.

Ṣùgbọ́n bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé 'tí' kò lè rọ́pò 'bí' àti 'kí' nínú (10-11), bí a ti rí i tí ó dígbà ń rọ́pò 'ni', 'pé', àti 'bí' nínú (4) àti (7-9) mú kí ó jọ gbogbońṣe atọ́ka amúpé. Àmọ́ ṣé oríṣi atọ́ka amúpé kan ṣoṣo ni a rí tí ó jẹ yọ nínú (4, 6-9) àbí ọ̀kan ṣoṣo kọ́? Bí wọn ò bá ń ṣe ọ̀kan ṣoṣo, kí ni (àwọn) ìṣesí wọn tàbí ìhùwàsí wọn tí ó yà wọn sọ́tọ̀ gédégédé síra wọn? Bí a bá fi lé ti ìhun nìkan, ó jọ pé oríṣi rẹ̀ méjì ni ó wà. Ọ̀kan ni ti inú (4, 6). Èyí yìí, tí a lè pè ní ayàsọ́tọ̀ (a-ya-ohun-sọ́tọ̀), a máa jẹ yọ ní ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn tí ó ní àpá tàbí àmì ìgbésíwájú (extraction site/mark). Ìkejì, tí a lè pè ní asopọ̀ (a-so-wúnrẹ̀n-pọ̀), ni ó jẹ yọ nínú (7-9). Onítibí ní tirẹ̀ a máa jẹ yọ ní ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn tí kò ni àpá tàbí àmì ìgbésíwájú kankan.

Àmọ́ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹ̀rí àfojúrí tí ó sì hàn kedere ni a fi ya oríṣi 'tí' méjì tí a wí níbí yìí sọ́tọ̀, síbẹ̀, bí a ṣe pín wọn sísọ̀rí yìí kò fi bẹ̀ẹ̀ tẹ́rùn. Ìdí kan ni pé, lójú tiwa, irú itú tí a fi 'ti' pa nínú (7-8) náà ni a fi í pa nínú (4). Bí èyí bá sì rí bẹ̀ẹ̀, ìsọ̀rí kan náà ni ó yẹ kí 'ti' ti inú àpẹẹrẹ mẹ́ta wọ̀nyẹn wà, kí ti inú (6) sì wà ní ìsọ̀rí tirẹ̀ ọ̀tọ̀. Síwájú sí í, ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà-orúkọ ní láti wá lẹ́gbẹ̀ẹ́ òsì 'ti' nínú, (6) – ìyẹn, bí òfin kankan kò bá ti pa ìrú ọ̀rọ̀-orúkọ tàbi àpólà-orúkọ bẹ̀ẹ̀ jẹ, bí ti inú (15e àti 18) nísàlẹ̀. Ọ̀rò-orúkọ tàbí àpólà-orúkọ kò kanpá rárá lẹ́gbẹ̀ẹ́ òsi 'ti' nínú (4, 7, 8). Fún ìdí méjì wọ̀nyìí, a óò pe 'ti' ti inú (6) ní '$ti_1$'; àwọn ti inú (4, 7, 8) á sì jẹ́ '$ti_2$'.

Iṣẹ́ ìyahun-sọ́tọ̀ ni '$tí_1$' wà fún ní tòótọ́, tí '$tí_2$'ní tirẹ́ sì wà fún tí isopọ̀. Ṣùgbọ́ń itúmọ̀. '$tí_2$' gẹ́gẹ́ bí asopọ̀ yàtọ̀ sí tí 'àti', bí ó ṣe hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nỳìí:

12. (a) Pé ó débí *àti* pé kò bèrè mi jọ mí lójú.
    (b) Pé ó débí $ti_2$ kò bèrè mi jọ mí lójú.

Ojú ìṣẹ̀lẹ̀ méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a fi wo '*pé ó débí*' òun '*pé kò bèrè mi*' nínú (12a). Ẹ̀wẹ̀, ojú ìṣẹ̀lẹ̀ kan ṣoṣo tí ó pín sí méji ni a fi wo ìpèdè méji kan náà nínú (12b).

Àpapọ̀ àpẹẹrẹ bí '*$ti_2$*' ṣe ń rọ́pò '*ni, $ti_1$', pe, àti, bí'* nìwọ̀nyìí:

13. (a) Mọ́tọ̀ kékeré kan ni mo rà *$ti_2$* mo rọra ń gùn lọ ibi iṣẹ́.
    (b) Iṣu ti, mo rà *$tí_2$*, mo bẹ *$ti_2$* mo gbé kaná ti jóná;
    (d) Kì í ṣe *pé* bàbá fẹ́ẹ̀ rí ẹ $tí_2$ ó ní kí wọ́n pè ẹ́ wá.
    (e) Bí ó bá dé ìbàdàn $tí_2$ ilẹ̀ ò tíì ṣú $ti_2$ ọkọ̀ èkó sì wà, èkó ló máa sùn lónìí.

Ẹ̀rí wà tí ó fihàn pé '$tí_2$' kì í ṣe atọ́ka amúpé, débi tí ó lè jẹ́ gbogbonṣe atọ́ka amúpé. Nínú (13), àwọn amúpé ni a rí tí ó so pọ̀. Ṣùgbọ́n ó jọ pé ó lè so gbólóhùn pọ̀ bá kan náà. Ẹ wo

14 (a) Níjọ́ náà, gbogbo wọ́n ń jó ni, $tí_2$ wọ́n sì ń yọ̀ ṣẹ̀ṣẹ̀.
   Fi wé: níjọ́ náà, gbogbo wọ́n ń jó ni. Wọ́n sì ń yọ̀ ṣẹ̀ṣẹ̀.
   (b) "Èkìtì kete! … Èyí ṣẹlẹ̀ lójú àwọn agbófinró, tí wọn ò sì fi tara tara dá sí i."
   Fi wé: Èyí ṣẹlè lójú àwọn agbófinró. Wọn ò sì fi tara tara dá sí i.

Nínú àpẹẹrẹ wọ̀nyìí, odindi gbólóhùn méjì adádúró ni 'ti' so pò. Ìyẹn nìkan kọ́; kò rọ́pò atọ́ka amúpé kánkan níbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn kejì, bẹ́ẹ̀ ni kò sì fi gbólóhùn kejì yẹn hẹ sára ìkíní.Nítorí ìdí èyí a kò lè pè é ní atọ́ka amúpé níbẹ̀. Bí kì í bá sì ń ṣe atọ́ka amúpé níbẹ̀, a jẹ́ pé kì í ṣe atọ́ka amúpé ni nínú (13) àti nínú (4, 7, 8) bá

kan náà. Èyí mú kí á túbọ̀ fura pé ẹ̀yà asopọ̀ kan ni 'ti' àti pé ń ṣe ni ó máa ń rọ́pò atọ́ka amúpé tí ó yẹ kí ó wà níbẹ̀rẹ̀ àwọn amúpé ti ó bá so pọ̀ bí ti inú (13, 4, 7, 8). Bí èyí bá sì rí bẹ́ẹ̀, ó bá wa fèsì ìbéèrè tí a ṣe lókè nípa bí 'tí' ṣe máa ń rọ́pò àwọn atọ́ka amúpé- ìyẹn, bóyá kánńpá ni àbí kànńpá kọ́. Kò kanpá láti so àwọn gbólóhùn tàbí amúpé pọ́. Ṣùgbọ́n bí a bá máa so wọn pọ̀ dandan ni kí á lo '*ti*$_2$' . Nítorí náà ń kọ́, ìlò rẹ̀ kanpá.

## Iṣẹ́ Àwọn Atọ̀ka Amúpé

Isẹ́ ọ̀pọ̀ nínú àwọn atọ́ka amúpé tí a tọ́ka sí lókè, àgàgà *'pé', kí, bí, àti tí$_1$,'* ni láti sọ gbólóhùn di amúpé tí ó jẹ́ àsọdorúkọ, aṣàpọ́nlé, tàbí ẹ̀yán. Ìbẹ̀rẹ̀ irú àwọn amúpé bẹ́ẹ̀ sì ni wọ́n tí máa ń jẹ yọ, pàápàá ní ìhun òkè (wo *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, o.i, 73-74, 80).

Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ,

15. (a) Ó dára *pé Olú lọ.* → Ó dára bẹ́ẹ̀
    (b) Ó dára *kí Olú lọ.*[2] → Ó dára bẹ́ẹ̀
    (d) Á dára *bí Olú bá lọ.* → Á dára bẹ́ẹ̀
    (e) Ó dára *tí$_1$ Olú lọ* → Ó dára bẹ́ẹ̀

Ó jọ pé a lè fi '*bẹ́ẹ̀* ' rọ́pọ̀ gbogbo amúpé inú àpẹẹrẹ mẹ́rin wọ̀nyìí, bí a ṣe fi hàn níbẹ̀. Fún ìdí yìí, ó jọ pé iyẹn fi hàn pé aṣàpọ́nlé (=àsọdorúkọ tí a fún níṣẹ́ àpọ́nlé ṣe) ni gbogbo amúpé inú rẹ̀. Àmọ́ ó kàn jọ bẹ́ẹ̀ ni o. Ẹ wo (16) tí ó jẹ́ ẹ̀dà (15).

16. (a) *Pé Olú lọ* dára.
    (b) *Kí Olú lọ* dára.
    (d) *Bi Olú bá lọ á* dára.
    (e)* *Ti$_1$ Olú lọ* dára.

Iṣẹ́ olùwà ni àwọn amúpé inú (16a-d) ń ṣe. Ìyẹn fi hàn pé àsọdorúkọ gidi ni wọ́n nibẹ̀. Ó fi hàn pẹ̀lú pé aṣàpọ́nlé gidi ni wọ́n náà nínú (15a-d) - nítorí pé àsọdorúkọ tàbí ọ̀rọ̀-orúkọ/àpólà-orúkọ tí a kàn fún nísẹ̀ẹ́ àpọ́nlé ṣe ni a mọ̀ sí aṣàpọ́nlé.

Ẹ̀wẹ̀, '*$tí_1$ *Olú lọ*' kì í ṣe àsọdorúkọ nínú (16e); ìyẹn ni kò lè fi ṣe iṣẹ́ olùwà nibẹ̀. Nítorí pé ki í ṣe àsọdorúkọ, kò lè jẹ́ aṣàpọ́nlé gidi nínú (15e) bá kan náà. Bí kì í bá ń ṣe àsọdorúkọ, tí kì í sì ń ṣe aṣàpọ́nlé, kìkì ẹ̀yán ni ó kù bá yìí tí ó lè jẹ́ nínú èdè Yorùbá. Ẹ̀yán sì ni ní tòótọ́, nítorí pé ohun tí Yorùbá máa ń wí dípò (16e ) ni

17. Lílọ $tí_1$ Olú lọ dára.

nínú èyí tí '*lílọ*' ti jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ, tí '*$tí_1$ Olú lọ*' sì jẹ́ ẹ̀yán aláwẹ́-gbólóhùn-ajúwe tí ó ń yán an. Àpapọ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ àti ẹ̀yán rẹ̀ ni gbogbo onímọ̀ ẹ̀dá-èdè mọ̀ sí àpólà-orúkọ. Nítorí náà ńkọ́, àpólà-orúkọ ni '*lílọ $tí_1$ Olú lọ*' nínú (17); kì í ṣe àsọdorúkọ ni (wo Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá, **Àfikún I**). Àpólà-orúkọ yìí gan-gan, tòun ti ori rẹ̀ tí o fara sin nínú àpólà-atọ́kùn tí atọ́kùn rẹ̀ fara sin bá kan nàá, ni ó wà ní ìpìlẹ̀ (15e).[3] Àpólà-atọ́kun yen gan-gan ni '*bẹ́ẹ̀*' rọ́pò níbẹ̀, kì í ṣe '*$tí_1$ Olú lọ*' tí ó jẹ́ amúpé aṣẹ̀yán lásán.

Wàyìí o, ẹ̀yán aláwẹ́-gbólóhùn-ajúwe kan náà tí ó ni orí nínú (17) ni ó jẹ yọ nínú (15e) láìní orí. Iru rẹ̀ náà ni ó jẹ yọ lápá òsì (18) láiní orí bá kan náà.

18. (a) Mo gbọ́ $tí_1$ wọn ń kọrin. = Mo gbọ́ *kíkọ* $tí_1$ wọ́n ń kọrin.

(b) Abájọ $tí_1$ wọ́n fi-ń kọrin. = Abájọ ìdí $tí_1$ wọ́n fi-ń kọrin.

(d) È é ṣe $tí_1$ wọ́n fi-ń kọrin? = È é ṣe ìdí $tí_1$ wọ́n fi-ń kọrin?

*Fi wé:* Kí ni **ìdí** $tí_1$ wọ́n fi – ń kọrin?

Kì í wáá ń ṣe ẹ̀yán aláwẹ́-gbólóhùn-ajúwe nìkan ni ó jẹ yọ láìní orí. Àwọn ẹ̀yán ajúwe náà lè jẹ yọ bẹ́ẹ̀. Bí àpẹẹrẹ:

19. Ó dé filà dúdú àti funfun. = Óˊfílà dúdú àti fílà funfun.

20. Ó dé aláwọ̀ dúdú àti funfun = Ó dé filà aláwọ̀ dúdú àti àwọ̀ funfun.

Àwọn ẹ̀yán aṣòǹkà dígbà máa ń ṣe bẹ́ẹ̀ náà. Àpẹẹrẹ ni:

21. Èkó méjì! Èkó méjì! = *Èrò* Èkó méjì! *Èrò* Èkó méjì!

22. Ó lọ Ìbàdàn kan lánàá. = Ó lọ *lilọ* Ìbàdàn kan lánàá

23. Ó lọ kan lánàá. = Ó lọ lílọ kan lánàá. / Ó lọ ọ̀kan lánàá.

Bí ó ti hàn kedere nínú gbogbo àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyìí (15e, 17, 18-23), ara ìṣesí àwọn ẹ̀yán inú èdè Yorùbá ni jíjẹyọ tí wọ́n dígbà máa ń jẹ yọ láìsí orí wọn tí ó fara hàn lápá òsì wọn. Ẹ jẹ́ kí á fi èyí sọ́kàn kí á fi wo àwọn ìpèdè Yorùbá bí

24. Kì í ṣe ni mo jí i. = Kì í ṣe *jíjí* ni mo jí i.

Gẹ́gẹ́ bí a ti wí ní abala **2** lókè, atọ́ka amúpé ni '*ni*'. Amúpé sì ni '*ni mo jí i*' ní jẹ́ nínú (24). Irú amúpé wo gan-an ni '*ni mo jí i*' níbẹ̀ – àsọdorúkọ ni, àbi ẹ̀yán? Ẹ jẹ́ kí á mọ̀ pé níbi gbogbo nínú

èdè Yorùbá, ń ṣe ni '*ni*' máa ń tẹ̀lé wúnrẹ̀n tàbi ẹ̀dà wúnrẹ̀n tí a ba '*tẹnu mọ́*;'[4] kò jẹ́ ṣáájú rẹ̀. Nítorí ìdí èyí, gbólóhùn kọ́ ni a 'tẹnu mọ́' nínú àpẹẹrẹ òké yìí – ẹ ṣàkíyèsí pé '*ni*' kò tẹ̀lé gbólóhùn tí ó wà níbẹ̀. Ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà-orúkọ ni ó gbọ́dọ̀ ti oríṣi '*ni*' kò gbólóhùn náà (wo abala **5** nísàlẹ̀) gbọ̀ngbọ̀n-ọ̀ngbọ̀n lápá òsì, gẹ́gẹ́ bí òfin ti ó de ìjẹyọ rẹ̀ ti gbà (wo *Ẹ̀kọ́ Gírámá Èdè Yorùbá,* o.i 71-73). Nítorí ìdí keji yìí, kì i ṣe ọ̀rọ̀-ìṣe '*ṣe*' ni a '*tẹnu mọ́*' lápá òsì nínú àpẹẹrẹ yẹn. Kò sì lè ṣe olùwà '*mo*' tàbí àbọ̀ '*i*' ni a '*tẹnu mọ́*' níbẹ̀, nítorí pé kì i ṣe bẹ́yẹn ni a ṣe máa ń '*tẹnu mọ́*' olùwà tàbí àbọ̀. Kìkì wúnrẹ̀n tí ó kù báyìí ó lè ṣe òun ni a 'tẹnu mọ́' níbẹ̀ ni ọ̀rọ̀-ìṣe 'jí'. Ìyẹn ni a fi mọ̀ pé 'jíjí' ní orí amúpé ìtẹnumọ́ inú àpẹẹrẹ náà làtì jẹ́. Ẹ ṣàkíyèsí pé ó fara sin (lápá òsì)[5] bí ti àwọn ẹ̀yán. tí a tọ́ka sí lókè. Èyí fi hàn kedere pé amúpé ìtẹnumọ́' a máa hùwà bí ẹ̀yán. Ó fi hàn síwájú sí i pé ẹ̀yán ni[6] gẹ́gẹ́ bí a ti wí ti-pẹ́ nípa 'topical qualifiers' nínú *Essentials of Yoruba Grammar* (pp. 40-42) àti láìpẹ́ yìí nípa 'ẹ̀yán aṣètẹnumọ́' nínú *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá* (o.i. 69-71).

## Èékì Àwọn Atọ́ka Amúpé

Àwọn atọ́ka amúpé inú èdè Yorùbá òde-òní tí àwa mọ̀, tàwọn tiṣẹ́ àti ìṣesí wọn (A ti ṣàpẹẹrẹ ìlò tàbí ìjẹyọ wọn lókè.) nìwọ̀nyìí:

> **$ni_1$:** atọ́ka amúpé fún ẹ̀yán; a máa tẹ̀lé wúnrẹ̀n tí ó bá bá rìn; a máa fa gbígbé-wúnrẹ̀n náà-wá-síbẹ̀rẹ̀-gbólóhùn; a sì máa ya ẹbírọ̀ (ẹbí-ọ̀rọ̀) sọ́tọ̀ sí ẹbírọ̀, bí ti 'ẹran $ni_1$ mo jẹ –', nínú èyí tí a ti ya '**ẹran** sọ́tọ̀ sí **gbogbo 'kòṣẹran**.' Ó yàtọ̀ sí $ni_2$, tí kì í fa gbígbé-wúnrẹ̀n-wá-síbẹ̀rẹ̀-gbólóhùn; tí ó sì wà fún ìtẹnumọ́ atọ́ka (Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá, o.i. 68, 77-78).

**tí$_1$:** atọ́ka amúpé fún ẹ̀yán; a máa tẹ̀lé wúnrẹ̀n tí ó bá bá rìn; a máa fa gbígbé-wúnrẹ̀n náà-wá-síbẹ̀rẹ̀-gbólóhùn; a sì máa ya mọ̀lẹ́bí-ọ̀rọ̀ sọ́tọ̀ sí mọ̀lẹ́bí-ọ̀rọ̀, bí ti 'ẹran tí$_1$ mo jẹ-', nínú èyí tí a ti ya **orísi ẹran** kan sọ́tọ̀ **sí gbogbo orísi ẹran** yòókù. Ó yàtọ̀ sí tí$_2$, tí kì í ṣe atọ́ka amúpé, tí ó sì wà fún ìsopọ̀ gbólóhùn tàbí amúpé méjì mẹ́ta irú kan náà, tí kò ní 'kí' níbẹ̀rẹ̀ wọn.

**bi:** atọ́ka amúpé fún àwẹ̀ gbólóhùn kání. Atọ́ka amúpé yìí wà ní ìbẹ̀rẹ̀ 'bóyá' nínú 'Mo fẹ́ẹ̀ mọ̀ bóyá ó wá àbí kò wá.' Ó yàtọ̀ sí **Bí** ti ibẹ̀rẹ̀ 'bí mo ṣe/ti wí;' ọ̀rọ̀-orúkọ ni eléyìí ní tirẹ̀ bí a ṣe wí ní ìtọsẹ̀-ọ̀rọ̀ 2 lókè (wo Essentials of Yoruba Grammar, pp. 17 & 36; Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá, abala 2.3.6.4, o.i. 86, abala 13.2.1, o.i. 249, àti o.i. 282-284; fi wé Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá, o.i. 195 & 197). Ẹ ṣàkíyèsí fáwẹ̀lì i aláfibọ̀ tí ó tẹ̀lé e nínú 'Mo fẹ́ẹ̀ dà bí i Jésù' (ní sísọ); wo Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá, o.i.20 fún ìtúmọ̀ àkíyèsí yìí.

**pé**; atọ́ka amúpé fún àsọdorúkọ onítumọ̀-ìṣẹ̀lẹ̀; àpẹẹrẹ: Mo gbọ́ pé Olú lọ. Ọ̀pọ̀nú rẹ̀ kò fi sérò rárá pé a lè má tìì jí nígba tí ó fi ń kanlẹ̀kùn kíkan kíkan mọ́ wa lórí ni aago mẹ́ta àárọ̀!

**kí**: atọ́ka amúpé fún àsọdorúkọ onítumọ̀-àṣẹ-ẹ̀bùrú tàbí ìtumọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀; àpẹẹrẹ: baba ní kí Olú lọ ní ìdájí. A ti sùn *kí ó tóó padà dé*.

## Ìgúnlẹ̀

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a kò wo ìṣesí àwọn atọ́ka amúpé wọ́nyíì délẹ̀ tìtorí ìṣoro èwolèwo (*indeterminacy*) tí irú ìwadìí bẹ́ẹ̀ sábà máa ń fún olúwádìí tí ó bá ń dá ṣiṣé, ó hàn lókè pé àwọn ẹ̀kọ́ tuntun wà tí wọn kọ́ wa nípa èdè wa. Ọ̀pọ̀ nǹkan ni ó sì wà bá kan náà tí wọ́n fi hàn pé a ò tíì mọ̀. Nítorí náà, ara ìdí tí àpilẹ̀kọ yíì fi wáyé ni láti gún àwọn mìíràn tí ó ní ìmọ̀ gírámà èdè náà ní kẹ́ṣẹ́ inú kí wọ́n ba dáwọ́ lé oríṣiríṣi àkànṣe ìwádìí àfara-balẹ̀ ṣe tí yóò jẹ́ kí á ní ìmọ̀ òdodo tí a mọ̀ pé a ó tíì ní bá yìí àti èyí tí a ò tilẹ̀ fura rárá bá yìí pé a ò tíì ní nípa wọn.

## Ìtọsẹ̀-ọ̀rọ̀

---

[1] Amọ̀ o, pé a lè rí àwọn tí ó ń sọ bá yìí:

*Nítorí tí kò padà tí kò sì fi ohùn ṣe méjì tẹ́lẹ̀ ni mo ṣe ń bínú sí i.*

A fura pé ohun tí wọ́n ń wí ní kíkún ni: Nítorí ***lílọ*** *tí$_1$ ó lọ tí$_2$ kò padà tí$_2$ kò sì fohùn ṣe méjì tẹ́lẹ̀...*

[2] Kí á má ṣe fojú atọ́ka amúpé irú ti gbólóhùn yìí wo wúnrẹ̀n '*bi*' nínú

*Ó dára bí Olú tí/ṣe lọ. = Bí Olú tí/ṣe lọ dára.*

Ọ̀rọ̀-orúkọ ni '*bi*' níbí yìí; kì í ṣe atọ́ka amúpé ni. 'Ti/sẹ' kanpá fún '*bí*' níbí yìí; kí í bá '*bi*' rìn nínú (15d); ó sì yàtọ̀ sí '*ti*' nínú *'Lọ wò bí Olú bá ti/tíì lọ*' (Wo abala 5 nísàlẹ̀.)

[3] Ẹ̀rí fún ohun tí a wí yìí ni pé ara bí a ba ṣe lè sọ (15e) ní kíkún ni:

Ó dára ni (ti) lílọ tí$_1$ olú lọ.
Ó dára fún lílọ tí$_1$ olú lọ.
Ó dára nítorí lílọ tí$_1$ olú lọ.

[4] A rí àwọn tí ó rò pé bí 'ni' bá tẹ̀lé gbólóhùn kan, odindi gbólóhùn yẹn ni a tẹnu mọ́. Ṣùgbọ́n ẹ wo 'mo máa ń ṣe jẹ́ẹ́jẹ́ ni nígbà gbogbo.' Irú àwọn àpẹẹrẹ bá yìí tí 'ni' ti jẹ yọ nínú gbólóhùn kò gbe èrò wọn lẹ́sẹ̀. Ohun tí àwa rò pé irú àwọn àpẹẹrẹ bẹ́ẹ̀ kọ́ wa ni pé, àpólà tí 'ni' bá tẹ̀lé nínú gbólóhùn ni a tẹnu mọ́. Nínú àpẹẹrẹ wa yìí, '(ṣe) jẹ́ẹ́jẹ́ ni a gbàgbọ́ pé a tẹnu mọ́. Nínú 'Mo máa ń ṣe jẹ́ẹ́jẹ́ nígbà gbogbo ni.' Ẹ̀wẹ̀, 'nígbà gbogbo' ni a tẹnu mọ́.

Ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó ní àbọ̀ kì í ṣeé dá tẹnu mọ́, tori òfin tí kò gba wúnrẹ̀n Kànkan láyè láti la àárín ọ̀rọ̀-ìṣe àti àbọ̀ rẹ̀. Èyí tí kò bá ní àbọ̀ nìkan ni ó máa ń ṣeé dá tẹnu mọ́, bí ti inú 'Ó ti lọ ni?'

[5] Ẹ jẹ́ kí á kíyèsí i o, pé irú ìpèdè yìí náà ni 'Ni mo bá tètè sá pamọ́.' = Òun ni mo bá tètè sá pamọ́' = 'sísá, òun ni mo bá tètè sá pamọ́.

[6] Fún ẹ̀rí mìíràn tí ojú àti èrò ti máa ń fò tẹ́lẹ̀, ẹ ṣàkíyèsí pé bí amúpé ìtẹnumọ́' ti máa ń yan àwọn arọ́pò-orúkọ gígùn tí wọn kì í sì í yan àwọn arọ́pò-orúkọ kúrúkú làti bá ṣiṣẹ́, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni gbogbo àwọn ẹ̀yán ti máa ń ṣe. gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ìwọ ni o jí i', àti ìwọ burúkú yìí; fi wé *O/Ọ ni o jí i.' àti o/ọ burúkú yìí. Èyí fi hàn kedere pé iṣesí 'amúpé ìtẹnumọ́' sí àwọn àrọ́pọ̀-orúkọ kò yàtọ̀ rárá sí àwọn wúnrẹ̀n tí gbogbo èèyàn mọ̀ sí ẹ̀yán. Fún ìdí yìí, a tún gbọ́dọ̀ ka 'amúpé ìtẹnumọ́' sí ẹ̀yán níbí, gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe tẹ́lẹ̀ lókè.

Wàyìí o, ìyahun-sọ́tọ̀ ní ó jẹ́ bí àbùdá àjọni ti gbogbo ọmọ inú ìsọ̀rí ẹ̀yán; kì í ṣe ìtẹnumọ́. Fún ìdí yìí náà, èrò tiwa níbí ni pé, ìtẹnumọ́ gẹ́gẹ́ àpèjúwe ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ gan-gan nínú àwọn ìpèdè bí ti 'ìwọ ni o jí i.' kò fi bẹ́ẹ̀ tọ̀nà. Àpèjúwe rẹ̀ òdodo kọ́ nìyẹn ! ìyẹbírọ̀-sọ́tọ̀ (wo abala 5) gan-gan ni ohun tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ nínú wọn. Nítorí náà ńkọ́, ìyẹbírọ̀-sọ́tọ̀ ni ó tọ́ láti máa fi juwe wọn àti láti máa fi pè wọ́n. Kí á máa pè wọ́n ní 'ìpèdè alátẹnumọ́/abìtẹnumọ́. Kí á sì máa pe ẹ̀yán inú wọn ní ẹ̀yán ayẹbírọ̀-sọ́tọ̀' dípò ẹ̀yán aṣètẹnumọ́/alátẹnumọ́.

Ojú ìgbàlódé tí a fi wo amúpé ìtẹnumọ́ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yán bá àwọn ẹ̀rí inú Yorùbá mu ju ojú àbáláyé tí ó kà á sí ẹ̀yà àpólà-ìṣe. Ó ṣàǹfàní jù ú lọ bá kan náà – ní ti pé ó dín irúwá-ògìrìwá wúnrẹ̀n tí ìmọ̀ àbáláyé kọ́ wa pé kì í bá àwọn arọ́pọ̀-orúkọ kúkúrú ṣiṣẹ́ kù sí oríṣi méjì péré nísìn yìí. Àwọn méjì náà ni (a) àwọn ẹ̀yán gbogbo àti (b) àwọn àpọ́nlé ọ̀rọ̀-orúkọ/àpólà-orúkọ bí dà, ńkọ́, náà, gúnmọ́, lásán, abbl. (wo Ẹ̀kọ́ *Gírámà Èdè Yorùbá,* o.i. 138-142 fún àpọ́nlé ọ̀rọ̀-orúkọ, àti **Ìgúnlẹ̀** ní o.i. 309 fún rírì dídín ségé-sègè àti àìhùwà-dọ́gba kù nínú èdè). Bóyá ìwádìí lọ́jọ́-iwájú yóò lè tọ́ka sí àbùdá àjọni tí ó kó àwọn méjì wọ̀nyìí pọ̀, yàtọ̀ sí pé ọ̀rọ̀-orúkọ nìkan ni wọn máa ń bá ṣiṣẹ́.

## Ìwé Ìtọ́kasí

Awobuluyi, O. (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. Ibadan: Oxford University Press.

Awobuluyi, O. (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*. Oṣogbo: Atman Limited.

Bamgboṣe, A. (1966). *A Grammar of Yoruba* (West African Language Monographs No. 5) Cambridge: Cambridge University Press.

Bamgboṣe, A. (1990). *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.* Ibadan: University Press Limited.